**Akiyesi**

A nfẹ Ẹniti yio ma ba wa ta Iwe Irohin Imọlẹ. Ni agbegbe Ilọrin tabi Ilu miran. Ẹ kowe si ọdọ Ọgbẹni R. O. Adedeji Esq: Ni P. O. Box 12. Ilọrin

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**Notice**

HELLO! HELLO!!

For all your Electrical appliances & work Consult:-

Shegun Elect. Stores.

Stockist of Elect. Cables, Fittings an accessories. Workshop & Showroom 15 Jebba St. (East) Oluste Metto.

VOL. III No. 148 MONDAY MAY 16 — MAY 22 1960 KỌBỌ KAN (1d)

# IMOUDU ati awon mefa ti o je Olori awon Osise ni ile ejo giga ju si ewon

MICHEAL IMOUDU ẸNI ỌDUN MERIN DIN LỌGỌTA TI O JẸ ALAGA ẸGBE TIRẸ TI Ẹ Y A-KAN NI TI ẸGBẸ APAPO OSIṢẸ NAIJIRIA, TI O TUN JẸ ALAGA BAKANA FUN ẸGBẸ AWỌN OSISE APAPO TI OKO OJU IRIN RELUWE, NI ILE ẸJO GIGA TI ASSIZES JU SI ẸWỌN OSU MẸTA TI ONISẸ ASEKARA NI ỌJỌ JIMỌ TI OSE TOKOJA.

IMOUDU pẹlu awọn Olori oṣiṣẹ mẹfa Haruna Adebọla, Ọlaolu Oduleye Okei Achamba, P. Thomas E. Offi, ati Peter Offi ti njẹjọ ni ile ẹjọ giga ti Assize l' Eko pe wọn jija igboro, awọn oṣiṣẹ ọkọ oju irin Reluwe ṣe eto ifihan ninu ọgba ile iṣẹ wọn ni ọjọ kẹwa oṣu kejila ọdun tokọja.

Ọdaran keji Haruna Adebọla ni ile- ẹjọ ni ki o ma lọ ni alafia nitori ko jẹbi ẹsun ti wọn fi kan a. Ile ẹjọ gba wipe nitotọ ni Adebọla kosi ni Ọgba Reluwe ni arin agogo meje abọ laro ọjọ yẹn titi di agogo mẹsan, nipa ẹri ti Ọgbẹni F.S. Mea Ewen ati J. S. George jẹ Adajọ wa sọ wipe iyemeji ti on ṣe nipa ti Ọgbẹni Adebọla yekoro nitori on ko lero wipe o ba wọn ṣe eto ifihan ni arọ ni arọ ọjọ na, ṣugbọn Adajọ wa ṣe afikun pe " Ori lo yọ ẹ.

Adajọ Ọgbẹni Bennet wa sọ wipe: " Gẹgẹbi aṣa ti awọn Odaran ba ti jẹbi ẹsun ti a fi sun wọn niṣe ni wọn ma mbọbẹ fun anu. Ti o ba jẹ wipe ẹjọ yi ti ba ọna imiran lọ nko ba ti mọ ọna imiran nipa iya jijẹ.

Awọn Ọdaran yi bi wọn ni Ipo ninu Ẹgbẹ awọn Oṣiṣẹ tabi wọn ko ni ipo, ọkan daju pe O l o r i Oṣiṣẹ ni wọn jẹ, nibi iṣẹ owo ti o tobi ju ni Naijiria, mo dẹ le sọ wipe mo gba si ohun aito, ati iwa-kuwa atipe yio jẹ ohun ti yio buru fun Ilẹ Naijiria ni ọ j ọ iwaju pe iru awọn Enia bayi ti ko mọ iwe ti ko dẹ ni ọgbọn jẹ awọn Olori awọn Oṣiṣẹ n i b i t i wọn le ni ohun lori awọn Alaimokan ati awọn ti a le tete tanjẹ (Iyẹn awọn Oṣiṣẹ)

Mo siyemeji pe ọkan ninu awọn Ọdaran wọnyi, (ki a yọ Ọgbẹni Adebọla kuro) le ṣe Olori awọn Oṣiṣẹ nibi kibi papa ni Ilẹ Naijiria, O yani lẹnu pe eyikeyi ni nu wọn papa Imoudu jẹ ẹniti otọ, lati jẹ Olori awọn Oṣiṣẹ, nibiti a le kakoti pe on ni o gba ara rẹ, mi ko lẹ sọ wipe a gba a, nitori ko ye mi to.

O jẹ ẹniti o ni inu fufu tabi ti o nse bi ẹniti aganmọ mbaja. O de jẹ eṣu beleke enia, iwa rẹ dabi ti ẹniti o fi ara eto Communist. Bi iwa rẹ ati iṣesi rẹ ko ba jọ bẹ

WO IYOKU LOJU EWE KERIN

## Ha! e'ı re melo?



Eyi yi ni Ẹrọ Alata to dara ju gbogbo eyi ti wọn ti nlo tẹlẹ ri lọ, lẹhin ata lilọ, o tun le lọ igbado ati Ọka-Baba, at Ẹwa ere oriṣiriṣi.

**£45 ni a nta** Pelu Ẹnjinni Pẹtrol tabi ati pẹlu Elẹtiriki Mutọ.

O WA NI ṢỌBU.

**Akoshile Brothers**

5, Balogun Street West,
P. O. Box 599
Phone No. 24395. Lagos

## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLỌWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ




MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pa taki ta ṣe ni Aṣẹpẹ fun Awọn ọmọde, ati nlo ogun yi fun ọpọlọpọ ọdun sẹhin pẹlu idaniloju fun Awon iṣẹ ribiribi ti o ti ṣe. MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to dara pupọ fun igbona iko, oruta Aipeti, Osi inu ọmọde, jẹdi j ẹ d i Kokoro ari ọmọde. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ki ọmọde ma nsun fọnfọn, o nmu ki ehin bibu jẹ irọrun fun awọn ọmọde. osi njoki awọn ọmọde tobi, osi nmu wọn dan ni awọ. Ẹnyin Abiyamọ, ẹ ṣu afojuba egbogi yi. Aran yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti ko-ṣe mani fun awọn ọmọde. Ijafara lewu pupọ. tete lọ ra ti ẹ si ile itaja Egbogi towa ni Adugbo rẹ.

**Igo kekere re jẹ 2/6d Igo nla jẹ 4/6d**

**LILO RE:- Sibi kekere kan lemeta lojumo**

*Wholesale Distributors*

A. K. KARIMU ANJOLA
& BROTHERS

6, Balogun Street West, Lagos Nigeria, Phone 22515 — 34, Docemo Street Lagos, Phone 204247

IMỌLE
ẸSIN ORO WA:
IMỌLE DE OKUNKUN PARADA
Editorial Works & Office
16, Bamgbose Strt,
Lagos
Telephone:- 21985
United Kingdom Representative
Publishing Distributing
177, Regent Street.

# Kini sababi ti o nso awon Obinrin di ONISINA

Oro mimo inu Bibeli so wipe, " ẸGBẸ BUBURU A MA BA IWA RERE JẸ " Bi enia ko ba njale, ti ko nfewo, ni ojo ti o ba rin po pelu Olosa, ti oju gbogbo enia si ri, bo fẹ bi o fi golu bora, aṣọ ole ni o wọ.

Ohun ti o nso opo awon obinrin di asẹwo tabi Onisina ni egbekegbe ti nwọn nko kiri. Tani ko mọ pe awon obinrin ni oju kokoro owo pupọ. Ko si obinrin ti ko wu wipe ki nwọn ma dan lode. Die ninu wọn lo ni iroju, tabi ti o ni suru wipe ki aṣọ ma teri mọ wọn lorun tabi ki wọn ma pano ninu aṣọ wọn.

Bi obinrin ko ba tilẹ ni ile lati ṣe sina, bi o ba nfi ojojumọ ri awon ẹlẹgbẹrẹ ti nwon udan lode ninu aṣọ ẹbi, aṣọ Emi-Oga, Lesi Mẹṣọ, Koro Adelo, Buba ile Iya Isadeko, Olẹ ntuntun lẹhin ogba, Olẹ nfi soro para lojo odun. Gbọ bi Abibu Olorin Eko ti fi awọn aṣẹwo korin wipe:- Aṣẹwo ko niran, ọmọ rẹ ko layọle kasa!

Opo ninu awọn obinrin lo nfi sina ṣe owo, bi iru awọn obinrin bẹ ba bimọ, ọmọ ale ni yio pọju ninu wọn, nitoripe nwọn ngbe ọmọ Oba fun Oṣun. Pupọ ninu agbole nla nilu Eko ni awọn ọmọ ale ti fọ patapata, eran ti o ba baja rin yio je imi, bi enia ba jẹ ọmọluwabi, ti o fi ọmọluwabi ẹgbẹ rẹ silẹ ti ko ba ko ẹgbẹ pọ, ti o jẹ pe awọn asa, olopipi, awọn alata lori bi dundun, elẹran lori bi ireṣi lọ mba ko ẹgbẹ, nigbawo ni ko ni di aṣẹwo.

Ni oni ni ao da aṣọ iyawo, lọla ni ao da aṣọ oku, nigbati obinrin ko ni ọkọ ti yio ṣe iranlọwọ fun, ti ko si ni iṣẹ lapa, kini oro pe yio fi da aṣọ na, bẹni tulasi ni ki o ba wọn da iru aṣọ bẹ. Nigbati ko ba si si tata loju-yanyan, o ni lati wọle tọ ọkunrin lọ, lati ibẹ ni yio ti gbe igba aṣẹwo dani. Aṣẹwo ko ni iran, Ọmọ rẹ ko ni ayọle o, Kasa!

## Egbe NPC. pa Kadara da

Lati Ọwọ:- M. A. ODEKUNLE LAGOS.

ILORIN Ọjọ Jimọh ti se 29/4/60, ni a ri ka ninu iwe Irohin Daily Service pe " Egbẹ Igbomina Parapọ (A.G.) jagun molu ninu Ibo Ibile ti Igboro Sharẹ Yoruba pe Ẹgbẹ Igbomina Parapọ wọle Ibo na laisi Alatako, ninu mọkandin ladọta (49) Kanselọ ti nwọn yan silẹ ni igboro Sharẹ ati agbegbe rẹ.

Egbẹ Igbomina Parapọ ko merindin ladọta (46) ninu rẹ laisi Alatako, o ku Ibo mẹta silẹ ti wọn o di bo fun.

Nigbati Ẹgbẹ Olomi (N.P.C.) gbọ eyi inu run nwọn, nwọn ni awọn ko gba bẹ, ayafi ki a tun gbo gbo ibo na di ni ọjọ ibo gan ni awọn nfẹ, eyi si lodi si ofin.

Ni ọjọ Monday 2/5/60 ti se ọjọ Ibo gan ni awọn N.P.C. lọ ṣa awọn Kansilọ wọn jọ ati ibiti awọn Ẹgbẹ Igbomina ti wọle nwọn ṣa gbogbo nwọn jọ, wọn ni Egbẹ Olomi ni o wọle.

Awọn N.P.C. Ilọrin abinu ori, nwọn nfi Fila dedi, nwọn ntu iṣẹ Ọlọrun wo. Ọlọrun Ọba nwo wọn niran.

Nitorina yio wu mi ki Resident Ilọrin ba ni foju to ọrọ na, ki awọn Egbo N.P.C ye huwa jagidijagan mọ, Ki nwọn gba ohun ati aye ti Ọlọrun to wọn si ninu Ibo ti Sharẹ yi.

Aiye ki se ti ẹnikan.

## Mensa ji Koko Obe

OMỌ ILẸ GHANA kan ti o nṣiṣẹ Mọle-mọle (Bricklayer) ti Orukọ rẹ njẹ Mensan Yasanu ti o si ngbe Opo-po Aiyetoro ni Apapa Ajegunlẹ ni o jẹ ipe ẹjọ pe o ji Koko Ọbẹ.

Ile-ẹjọ sọ wipe ẹdaran yi wọ ile kan ni Opopo Layinka ni Ajegunlẹ nibiti wọn lo ti ji Koko Ọbẹ yi pẹlu awọn nkan imiran Apo Ewa ati Basin Iresi.

Wọn fi ẹjọ rẹ si ọjọ Kẹrindinlogun oṣu June.

Bi o ba ti nlọ si, ẹ o ma gbọ nipa rẹ.

# OTITO NI OLORI IWA

Lati Ọwọ:— JOSHUA A. POPO-ỌLA. (ESIẸ)

NI IGBAKAN Awọn ọmọde mẹta kan wa. Wọn a si ma sire pọ ni ile ọga wọn. Oruko ekini a ma jẹ. Bi oju ri ẹnu adakẹ, ekeji njẹ bi oju ri ẹnu a sọ, ẹkẹta njẹ Asoro di bi bara mẹta.

Ni ọjọ kan bi awọn ọmọde mẹtẹta yi ti nṣe re po ni ile ọga wọn. Wọn digbo lu jigi nla kan ti owa ni ile ọgo wọn, jigi na yi lulẹ oba fọ, ọrọ na wa di womi-nwo -ọ ekini ti orukọ rẹ njẹ bi oju ri ẹnu adakẹ. Damọran wipe ẹnikeni ko gbọdọ jẹwọ bi jigi na ṣe fọ. Bi ọga awọn tile ma lu wọn pa wọn ko gbọdọ tu aṣiri yi. Ekeji ti anpe ni bi oju ri ẹnu a-sọ wipe o san ki a jewọ bi Jigi yi se fọ ki a dẹ jiya si nkan buburu ti a se jupe ki a purọ ti yio jadi ni ijọmiran, ki a ma ba jẹ Ajẹpele iya. Ekẹta ti orukọ rẹ njẹ Asoro di bi bara mẹta dahun wipe aṣiri yi ṣoro bo, nigbati ohun wa ko jẹ ọkan ekinni fẹ jẹwọ, Ekeji ko fẹ jẹwọ emi ko fẹ ki a parọ ki a ma ba ba oruko wa jẹ lọdọ ọga wa ati Aladugbo wa.

Ọrọ na so Ọlọgbọn kọ o so Were kọ. Ti ohun tẹnu Oga wọle de O ba wọn nibi apero yi loju kanna. Bi Ojuri ẹnu asọ dọbalẹ o bẹrẹsi bẹ Ọga wọn fun idariji. O jẹwọ bi Jigi ti se fọ Oga wọn ronu titi ko si na wọn.

Nitoripe wọn jẹwọ, nwọn si dupẹ lọwọ ọga wọn fun idariji ti wọn ri gba. E jẹki t'ọmọde t'agba wa na le fi eyi se arikọgbọn ki gbogbo wa si le jẹ Olotọ. Ki Aiye le yẹ gbogbo wa.

# Omo Aganyin to lo ko ise agbowo ninu oko Ofurufu



Awọn ọmọbinrin ti a nwo ninu aworan yi, ni awọn ọmọ ilẹ Aganyin (Ghana) ti nwọn lọ kọ iṣẹ agbowo lati ma ṣiṣẹ ninu ọkọ ofurufu. Orukọ wọn niwọnyi. Miss. Star Annan (on ni nwọn fi jẹ oye Miss. Ghana fun ẹwa rẹ ni ọdun 1959) Miss gloria Johnson lati ilu Axin ati Miss Janet Snowdon lati ilu Accra.

# Won da Egbe Nawair -ud-Deen sile ni Enugu

ETO IDA EGBE Nawair- ud- Deen sile ni Enugu ti i se Olu Ila Orun ni a se ni ojo ketadinlogun osu Kerin odun (A p r i l) ni odun ni. Mallam Altine Umoru Mayor Enugu ni o se Alaga ojo na

Ninu oro re Mallam Umoru kan sara si Egbe Nawair ud Deen fun irinan si iwaju ati igbiyanju lati wa da egbe na sile ni Ipinle Ila Orun nibiti o ni e k o ti Islam ni won nwa Oluko fun.

Ni ibere awon Asoju ti Olori I l e egbe ni o ko se eto idasile egbe na. Awon Alhaji Makanju Alufa H. Y. Dindi Raji Alade Omo Iya R. A. Bello Olayori B. A. Daodu. G. A. Fabunmi S. O. Lawa ati S. A. Okanlawon Won wa so wipe iko Enugu ni o di iko adorin ti egbe Nawair-Ud-Deen at pe odun 1939 ni awon ti da egbe yi sile ni Abeokuta.

Won ni ile-eko ti egbe na ni kakiri ati ni Ghana je ogorun le merin ni odun 1959. Won ni iranlowo Ogbeni Hassan Akinyode loje ki awon si i l e eko fun kiko ede Larubawa ni Kano ti awon fi egberun meji poun ko nwon ni lowo-lowo yi, awon ti si ile eko giga ti awon yio tun ko si ona Ibadan.

Ninu o r o igbehin Mallam Umoru so wipe " on yio sowopo pelu iko Enugu. Ki won ri eto awon Iko ti Enugu bebe fun kiko Ile Iwe ti Larubawa ati ti Gesi kakiri Ipinle Ila-Orun.


## FOR SALE

## Second Handed Cutting Machine (GUILLOTINE)AT Moderate Price

Consult:-
Manager Modupe Printing Press
16, Bamgbose Street, Lagos. Phone 21985



## Iwe ilana Ifa, Yanrin tite, Etutu Sise. Iwosan ati Egbogi Ajebidan.

Ti o ba ni Iwe yi lowo- Oso Aiye, Aje Enia - majeki Tenisunwon, Alapeta ati awon ibaba ati ikoko ko na lagbara lori re Ohunkohun ti o ba dawole rere ni yo ma jasi Babanla Awure ati Ogun Ajebidan wa nibe pelu tete ra tire ki o to tan, awon Babalawopapa wa odura lodo wa ni. Iye Owo 10/6d.

2. Itumo Ala ati Ayewo Odu Ifa 2/6d.
3. Agbara Igba Iwase Yoruba ati Psalm Ajebidan 3/-
4. Gbedegbeyo Hausa 2/6 5. Itumo Ami Ara 3/-
6. Ewo Yoruba ati Etutu 3- 7. Ma Iomo y o m o Arofo 1/6d Turari Itaja Adura Tetedamilohun, ati Isegun Aie pelu Psalmu Ajebidan 15/6.

Fi Owo ranse si Ogbeni J.O. Shoyinka 6, Ojo Road Odunabor-Mushin.



## AKIYESI PATAKI

## Antoin Tabs! Antoin Tablets!! Antoin Tablets!!!

KABIYESI,! KABIYESI OBAKOSO MO FENUN SO OWO

Eyin omo ara aiye mo ba yin so lekunrin, lobirin, lagba ati lomode E ku a fo juba Egbogi pataki ti a se Iwadire fun:- Ako Igbona, Ara riro, LukuLuku ati Iba ponju, (Yellow Fever) pelu Ito pupon lati owo awon Dokita wa ni Ilu Oyinbo.

(Reduces Fever, Relieve Pains)
For Children and Adults.

O daju Hawun Irohin ko to afojuba.

Bere lowo Onisegun Adugbo re, tabi Lowo Ogbeni wa.

Hassan Commercial Medicine Stores
18A Bishop Street, Lagos. Phone 23745


# Bismilai Rahmoni Rahmi.

# NIPA ISLAM

Lati Owo:— ALFA HUSAEN MUHAMAD.
No. 10A. Thomas Street, Lagos.

## Ise Haji' (Apa-karun)

"LEHIN NA Je ki won se ise won ki won si mu awon ileri won se ki won si yi po i l e lai-lai na." :— (HOLY QURAN.)

Gegebi mo ti se wi ni ije-jo, eye kan na ti enia ba ti yo si Igboro Moka ni yio ti kun fun idunnu ati iberu Olorun. Lai ko ni yo si ibi kankan, ile Oluwa Kaaba ni yio si danko lati se awon isin akoko 'Umura" pelu aso Harami nwon, yio okan ninu awon ona Kaaba, na wole eyiti o je ile nla ti asi fi a s o Siliki dudu bo ni arin Ile Oluwa.

Awon Maitawafi (Guides) ni yio mu e n i a rokirika ise na ni emeje pelu wiwi awon gbolohun adura ti ati se ni eto fun. Lehin eyi si ni won yio lo ibi Hajaral - Aswad Okuta ti a fi se iranti Abrahamu ni ara eyi ti o lo fun mimo Ile na lehin omi ti o pa aiye re ni igba Anabi Noah.

Awon Enia a ma se ariyanjiyan nipa fifi o w o tabi enu kan okuta yi. Awon ti osi ni aisan Keferi lokan atun ma ro wipe bibo gidi ule ni won nbo ni ohun Islam ko ni nkankan ti o fi ara jo ebora rara tabi isin okun-kun. Awo Nipataki mo fe ki awon Oluka I w e Irohin Imole mo daju pe Anabi Mohammad fi enu ara re so nipa Okuta yi pe fifi enu tabi owo kan ko je nkankan tayo wipe ki a le woye Olorun nipa pipe ti oti wa ni ibe, aiko si se ikankan ninu mejeji ki akan fi oju ri lasan ko ba Aji enia je beni, ko din ise enia ku. Sugbon ki ase be kun fun alubarika.

Lehin fifi enu tabi owo kan Okuta yi ni awon Alihaji yio wa lo si Mokamo Iburaimo, ni ibi oripo ti okoko fi ile Oluwa lele si ni orile aiye. Won yio si gba awon adura ti ati se ni eto kale si ibe. Lehin eyi ni won yio jade kuro ni inu Kaaba lati lo sa ere emeje larin awon oke Safa ati Moriwa. (about 300 yards apart) Alihaji gbodo sa ere na ni iranti ere ti Hajara nsa lati wa omi fun omo re ni igbati won ju si arin a g i n j u igbe, ti osi nri ojiji lasan (mirage) ni ona mejeji na ti o nro pe omi ni fun omo re Isimaila.

Laiko ni sin mi awon alihaji yio sa ere yi ni emeje pelu wiwi awon adura aye re. Awon arugbo awon aro awon alaiko le a yio wa ni ori amoku.

Bi won ba si pari re won yio lo si ibi omi isun ti aope ni ZamZam eyi ti o jade fun Isimaila ni kini won yio si bu we ni ibe lehin ti won yio ti fa ori won ti yio si ti bo aso harami won pa mo, titi di ojo arafa.

Ni ipari Umura yi ni Alihaji di eniti a tunbi kuro ninu ese oti we oti mo osi ti yowo ninu gbogbo jangbonjangbon aiye.

Oku kio wa lo wo si ile ibi ti oba de si ki osi ma reti ki won si ilekun Baetil Atiki, ki o le wo arin gbungbun ile oluwa ile yi ni Oluwa so oro re ninu kurani pe oje ile akoko ti a fi lele fun omo enia ni orile aiye lat josin fun Olorun nibe. Won ki saba si ile na sile ni igba gbogbo, ayafi ki Alihaji ni akiyesi dada ki o si ma so ni osan ati ti oru, nitori ti enia poju ti won yio fe wo ibe. oju ona re si kere otun wa ga bi ese bata meje si ile.

pelu ijangbon nla ni enia fi ngun, nigba miran pelu akaba ati ni igba miran pelu okun ti won yio ro wa si ile, ti won yio tun ma gun ori ara won pelu.

Bi Alihaji ba ti ri eyi se tan oku ki o ma wa lo sin mi ni ile titi di ojo Arafa ki o si ma gba adura pipo papa ki o ma to kurani bi oba mo kewu. Ki o ma se lo ara re ni ilo kulo nitori are ki o ma si se ijangbon ti ole fe de itimole ti ko fi ni ri aye jade lowo awon olopa ni ojo Arafa.

# MA FI OWURO S'ERE APA 13

Lati Owo:- J O. SHOYINKA (Mushin)

AKIYESI:— Mo fi eyi ki awọn Oluka Itan mi pe ẹ ku atijọ, ẹ jọwọ ẹ maṣe binu pe ẹ ko ri Itan mi lasiko, aiko si ni Ile mi ni, lati isisiyi-lọ ẹ o maka itan mi lọsọsẹ lagbara Oluwa.

BI AKỌ-OKUTA Ati awọn ẹlẹgbẹrẹ ti nfi awọn Alujannu ṣẹfẹ nitoripe nwọn ti fi Ifoju lu nwọn, nwọn ko mọ pe Babalawo awọn alujannu ti lu gọ si ori igi, lojiji ni o ta akọ-okuta ni ọfa ni atari, eyiti ọfa yi iba fi wọ ọ ni atari, nṣe ni o ta danu o si run wẹwẹ, nigbana ni akọ-okuta to ewu nbẹ lo ko longẹ. o siju woke oiri Babalawo awọn alujannu o pe e, oni mo o ni o ta mi ni ọfa ni atari ? o ko mọ pe ẹnu ẹiyẹ ki ran okuta ni ? ohun ti mo sọ awọn ara rẹ da, ngo sọ-ọ di ohun ti o buruju bayi lọ, babalawo ko le gbin pẹnkẹn akọ-okuta tun kigbe le lori pe ki o yara sọkalẹ, ṣugbọn eyiti iba fi sọkalẹ o rọra lẹkẹ mọ ori igi. o si fa ọkọ yọ pe ti akọokuta ba ngungi bọ wa si ọdọ on, on yio tu ni ifun danu. Akọ-okuta si ti mọ ero ọkan rẹ, o si sọ fun pe Babalawo o ba rọra sọkalẹ iba dara fun ọ, Ida rẹ ko ba mi lẹru, ko si le ran mi nitoripe ọmọ ogun ni mi. Bi o fẹ ki o sọkalẹ ni ẹrọ, bi o ko ba si tete sọkalẹ, iwọ yio sọkalẹ ni ele.

Babalawo fi gbigbọ se alaigbọ ko tilẹ da Akọ-Okuta lohun inu wa bi Akọ-okuta lohun, inu wa bi Akọ-Okuta o tẹnu bọ ogede, o wa fa Akaraba yọ, o bẹrẹsi kan, lairotẹlẹ ni Babalawo awọn Alujannu jabọ pọọ iba ja lulẹ lasan ibadara, ṣugbọn nṣe ni o jalu ọkan ninu awọn Afọju Alujannu o si ṣẹ lọrun, bayi si ni Alujannu yi kigbe Oro ku.

Nigbati o de ilẹ tan, Akọ-okuta ni nko sọ fun ọ pe la-la ti o lọ si oke, ilẹ lo nbọ.? Oju koju nisisiyi ewo ni siṣe nba bẹ ọ lori nisisiyi ṣugbọn ti ṣo-ṣo moji ko ba fori sọra nwọn ko ni dun to, ti ako ba kọlu ara wa kinto pa ọ, iwọ yio ro wipe agbara Alujannu ju ti enia lọ, Ọlọrun ti fi wa ṣe Olori nyin O si ti la na nyin nitorina, ẹ ki se rin ni ọsan gangan a fi oru, jọwọ Babalawo ọrun ndifa Elejiogbe, gbera sọ ọjọ nlọ.

Akọ-Okuta tun sọ bayi pe bi agbara mi ti damiloju to, ngo la awọn ọmọ ẹhin rẹ loju ki nwọn ba le ri ohun ti yio ṣẹlẹ si ọ, ki ẹ si pa ara nyin pọ se ọkan irun kan ẹ kole tu ni ara mi.

Obu ẹrapẹ nilẹ, o da si nwọn loju oju nwọn si la wa a. Iyalẹnu ni lati ri Babalawo nwọn ti o wo lule bi ọganwo igi, ojora mu nwọn nitoripe on ni nwọn gbẹkẹlẹ, eyi paapa si jẹki wọn tun bẹni Akọ okuta pe Alujannu tiẹ ju ti nwọn lọ.

### BABALAWO NWỌN FI ITIJU KARUN

Babalawo fi itiju karun nigbati o ri awọn ọmọ ẹhin rẹ, o pe Akọ Okuta ni ija, ẹsẹ ni Akọ Okuta kọkọ na sii, nigbati o gan ẹsẹ yi o bẹrẹsi gbera dẹdẹdẹ kakiri agbo, Akọ Okuta dẹra silẹ fun o si rope on yio fi ẹsẹ gbigbe yi la mọlẹ, lojiji ni Akọ Okuta na ni efaṣẹ o si tun subu wogira. Akiyesi lọsẹ to nbọ ẹ o ma ka apa (14) gẹgẹbi ija ti ye de oju rẹ, ti awọn Alujannu si fi bẹrẹsi gbeja Babalawo nwọn.

---

Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 10, Bamgbose street, Lagos Phone: 21905. Olotu: E. A. Adeniji 51 Tejuosho Street Suru-Lere YABA
FUN OWO IROHIN IMOLẸ ODUN KAN
EKO - Ṣile Mẹrin ati Kọbọ Mẹrin (4/4d)
Ilu miran ni Naijiria ati OKE-OKUN Ṣile Mẹfa ati Kọbọ Mẹfa (6s/6d)

# Canada yio sowopo pelu ile NAIJIRIA

Aworan ẹniti ẹnwo yi ni ti Ọgbẹni T. Lem Carter, oluko agba ti ilẹ Canada ni Naijiria ( Canada High Commissioner).


ỌGBENI LEM CARTER

Ọgbẹni Lem Carter pe apejọ awọn oniwe irohin ni ọjọ alamisi ti ọsẹ to koja ni ile rẹ ni Ikoyi, nibiti o gbe sọ wipe, on wa lati ri i pe ilu on Canada jumọ ṣe ọrẹ papọ ati jumọ sowọpọ pẹlu ilẹ Naijiria, ni ọrọ iṣelu ati ni ti owo.

Oni ni oṣu Kẹsan ọdun ni Akọwe owo on yio wa si ilẹ Naijiria lati ṣe iṣẹ ribiribi nipa owo larin ilẹ Naijiria ati Canada.

Lori ọrọ iya-enia-dudu sọtọ ti madaru Ijọba funfun ti Afrika Gusu nṣe Ọgbẹni Carter sọ wi e Ijọba on ko fi ara mọ iyara-ẹni-sọtọ niti awọ ati ti ẹya orilẹ ede.

Ọgbẹni Carter sọ wipe owo ti o wa larin ilẹ Canada pẹlu Naijiria ko pọ rara, nitorina on yio ri si pe owo larin ilẹ mejeji yio pọ si ni ọjọ iwaju.

O wa pari ipade rẹ pelu awọn oniwe irohin pe dundun inu Ijọba ilẹ on lo jẹ lati ri pe Naijiria yio gba Ominira ati pe yio wa ninu awọn orilẹ ede (Commonwealth) ti o faramọ eto ṣiṣe ilu ti ilẹ Gẹsi. O ni on lero pe ilẹ Canada yio da iṣe owo silẹ ni Naijiria.

---

# Imoudu ati Awon Osise Mefa lo si ogba ewon

OBERẸ LATI OJU EWE KINI

o dabi ẹnipe emi ko mọ ohun ti o njẹ Communism.

Gbogbo rogbodiyan na farajo rogbodiyan ti communist le da silẹ ti Ijọba kẹ re ba le jọki irufẹ nkan bẹ ma ṣẹlẹ nibi ile owo ọkọ ti o tobi ju ni Naijiria, ti o jẹ iru awọn enia bi awọn odaran yi lo gbọdọ ma paṣẹ ọrọ, gẹgẹbi irosi ti emi, Ijọba ko iṣẹ rẹ daradara fun ilu Naijiria ati awọn oṣiṣẹ

Bakanna ni Ọgbẹni Adajọ Bennet sọ lori awọn ọdaran ti o ku bayi lo dẹ ti ṣe idajọ rẹ Imoudu ẹwọn oṣu mẹta mẹta fun ẹṣẹ rẹ Oduleyọ, oṣu kan, Thomas ki o san poun mẹwa tabi ẹwọn oṣu kan. Ottu ọsu kan. gbogbo ẹwọn wọn jẹ ti oniṣẹ aṣekara.

Peter Ottu Poun marun tabi ẹwọn oṣu kan.

Wọn ti gbe ẹjọ wọn lọ si Ile ẹjọ ko tẹmi lọrun, ṣugbọn kakaki wọn jẹ ki nwọn duro fun awọn' wọn ni awọn yio joko lọgba Ẹwọn di igbakugba ti Kotu kotẹmi lọrun ma gbọ ẹjọ awọn Agbẹjọro wọn ni Aliyi-Ekinch.

---

# L'oni ni ejo Awon ti o pa Egungun Bamgbose

Loni ni ile ẹjọ ni Eko yio gbọ ọrọ ẹjọ awọn ẹni mẹta ti wọn mu pe awọn ni o pa egungun ni opopo Oshodi ni alẹ aisun Ajinde.

Awọn ọdaran na ni Shitta, Raimi, ati Ereibeji.

Egungun ti wọn pa ni Mufutau Idowu Bamgbose.

Nigbati wọn kọkọ gbọ ẹjọ wọn adajọ sọ wipe on fi ẹjọ wọn di oni lati fun awọn Ọlọpa laye lati wadi ọrọ wọn.